## Ṣọra fun jẹgudujẹra ati awọn itanjẹ lakoko ajakaye-ajakale-arun COVID-19

**Awọn ọdaràn ti nlo ajakalẹ-ajakaye ti COVID-19 lati ṣe itanjẹ ati jibiti - maṣe ko si wọn lowo.**

COVID-19, aarun ti o waye nipasẹ coronavirus tuntun yi ti wa di ajakale arun ti o kariaye. Awọn ọdaràn ni gbogbo agbaye n lo idaamu yii lati tan awọn ara ilu jẹ, ni paapaa julo, awọn ti o ku die kaato fun lawujo. Awọn egbe ti o n se idaabo bo awọn ara ilu lowo iwa jegudujera ti orilẹ-ede UK, royin ilosoke 400% ninu iwa awọn  jegudujera ti o ni ibatan coronavirus ni Oṣu Kẹta 2020.

Ọlọpa ati awọn ara ijọba miiran n ṣiṣẹ papọ lati polongo awọn itanjẹ wọnyi ati rii daju pe gbogbo eniyan ni ifunra ati  iṣọra  si iwa jegudujera.

Ile igbimo Ẹjọ giga ti ilu UK ti pin awọn imọran wọnyi:

**Duro**: Gba akoko diẹ lati ronu ṣaaju ki o to  fun enikeni ni owo rẹ tabi alaye oroti o le koba ipamọ re.

**Ipenija**: Bi ara leeere wo. Ṣe o le jẹ iro? Ki n se oun aburu lati kọ ohun ti a ba fi lo e.  Awọn ọdaràn nikan ni yoo gbiyanju lati sare ta ounkoun fun ọ tabi lo ijaaya fun ọ.

**Ṣe idaabobo**: Kan si ile ifowopamọ rẹ ati awọn igbimo Action Fraud lẹsẹkẹsẹ ti o ba ro pe o ti bọ si ọwọ awọn eletekete yii.

A ti finukonu lati se apapọ awọn ijabọ oriṣiriṣi ti awọn oniitanjẹ yii n lo lati ṣe atọna fun ọ lati ṣọra fun.

* Jọwọ ṣakiyesi pe awọn ona miran le wa ti ko si ninu atona yii, ti awọn odaran le lo lati se ijamba wọn, nitorina nigbagbogbo ni ki a maa ṣọra.

• Idanwo Ajakale arun: Owọ NHS UK nikan ni a ti le ri awọn ohun elo idanwo ti o jẹ tooto ti o si dangajia.

• Awọn ajẹsara / Awọn imularada: Lọwọlọwọ kò si ajesara tabi iwosan fun COVID-19.

• Aiyederu Oja: Pupọ ninu ọja ti o n se idaabobo ni owo re ti losoke bee gege ni aiyederu oja ti gbode kan ti owo re si ti gọbọi. Ninu re ni awọn ipara owoti o n pa kokoro, iboju ati be be lo.

• Alabara ounje abi Oogun: Awọn ọdaràn ti n dojukọ awọn eniyan ti o ni ipalara ni ẹnu-ọna wọn lati ranwọnlowo ba wọn ra ounje abi oogun.

• Alagbafọ: Wọn a tun polongo pipese awọn iṣẹ ṣiṣe lati fọ ile mọ fun arun ajakale yii.

• Iroyin Itanje ati alumokoroyi lori erọ alagbeka ati imeeli: Ṣọra fun awọn ironyin lori ero alagbeka re ti o ni ki o te ounkoun ti o le je ki awọn madaru yi ni aaye lati ja o lole.

Awọn apeere imeeli ti awọn alabojuto Action fraud ti damo nipasẹ ipa etan niyii:

1. Awọn arekereke ti o ṣe bi ẹni pe wọn wa lati ẹgbẹ iwadi ti o ṣe agbekalẹ Ile-iṣẹ fun Iṣakoso ati Idena Arun (CDC) ati  Alamojuto eto ilera agbalaaye, World Health organization (WHO). Wọn a paro wipe awọn ni oruko awọn ti on I arun yi ni agbegbe wọn.

2. Awọn alarekereke yi a tun ni wipe awọn ni iroyin ti o peye lori arun yi, wọn a si funni ni itona si ori ero wọn lati maa gba iroyin ojoojumọ.

3. Awọn alarekereke odaran ti n se ifiranṣẹ idoko-owo ati imọran sogun-dogoji fun awọn eniyan lati lo anfani iselẹ ajakale arun coronavirus.

4. Awọn arekereke ti o ṣe bi ẹni pe wọn wa lati HMRC ti n se eto idapa owo-ori ati darí awọn olufaragba si ori wẹẹbu iro lati gba awọn alaye ti ara ẹni ati ti owo wọn.

Ti iwọ tabi ẹnikan ti o mọ ba ti kosi owo awọn odaran wọnyi, mase jafara lati so fun awọn Action Fraud lori ayelujara ni www.actionfraud.police.uk/ tabi nipa pipe 0300 123 2040.

Fun imọran ati alaye lori bi o ṣe le ṣayẹwo ti ohunkan le jẹ ete itanjẹ kan, ṣabẹwo si ni: www.citizensadvice.org.uk/consumer/scams/check-if-something-might-be-a-scam/.

* A pese itumọ yii lori ipilẹ atinuwa nipasẹ awọn ẹgbẹ wa ti n se itumọ adani*

Yoruba: Adewale